The Hon The Chief Secretary


# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han fun awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead

Vol I. No. 24. SATURDAY, DECEMBER 23, 1922. Fourpence.



*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### ỌKUTỌ, AJAGUN M'OLU.

Ọrẹ ati ẹlẹgbẹ wa ni Ile-iwe kanna Ọgbẹni S. A. Baptist ati aya rẹ de lati Ilu-ọba ninu ọkọ titun oni-manamana "Adda" ni *Thursday* ọsẹ to kọja, ọrẹ wa na ti gba oye *Lawyer* bọ on si ni ko-nko pọnun mẹdọgbọn (£25) yẹn ru. !!!

### ẸGẸ LO YẸ CHARLIE.

A ba Ọgbẹni J. Egerton Shyngle yọ fun ọmọ rẹ Charlie ti a gbọ pe o ti wọ "Igbalẹ" (*Inner-Temple*) fun kikọ iwe fun işẹ *Lawyer* gẹgẹ bi baba rẹ "Lọya Jiga" o bẹrẹ si işẹ yi ni ọjọ kejila oşu ti ọhun ni Ilu-Oyinbo.

### KITOYI?

Bi Ẹni-ọwọ Fekemo Johnson ti Ijọ Wesley ti lọ ki Ọgbẹni C Ibare-Akinsan ni Ita Balogun ni alẹ ọjọ kẹrinla oşu yi, ti o si gbe kẹkẹ-ologere (*Bicycle*) rẹ si iloro ile na, ti o si goke pẹtẹsi lọ, bẽni awọn "ọmọ jaguda" kan fọn kẹkẹ na lọ, ti o si di ogun ti Ẹni-ọwọ yi ni lati fi ẹsẹ şã lọ si ile.

### Ẹ KU AFẸRẸ YI!

Ọyẹ gb'ode kan nisisiyi lati ọsẹ to kọja, o si mu oju ẹni funfun ruru, bẹ̃ni o mu omi tutu pẹlu, to bẹ to fi le sọ awọn enia miran di "a r'omi-ma-wẹ."

### OṢE, ARAKURIN MI!!!

A ba Bãlẹ Ilu (Ọgbẹni HENRY CARR) kẹdun gidigidi nipasẹ iku aburo rẹ Ọgbẹni ABRAHAM R. GEORGE, igbakeji akọwe agbã, ni Ile iṣura ọba (*Treasury*), ti o ṣẹlẹ ni Ile-alarun ti DR. ADENIYI JONES ni ọjọ kẹrinla oṣu yi, mã j'ọkun, mã j'ekolo."

### OFIN, TOTO FŨN.!

Anu ẹlẹgbẹ wa kan Ọgbẹni W. C. LABOUR Oniwe-irohin kan ti a npe ni *Nigerian Herald* ti o nṣe ni ilu Onitsha, ṣe ni, fun gbigbọ ti a gbọ pe Ijọba mũ san ọgbọn pọnun (£30) s apo Ọba fun ai-jubà ofin Iwe-irohin gẹgẹ bi a ti lana rẹ silẹ, ki o to bẹrẹ si iṣẹ na.

### ARA ILU, Ẹ WÁ GBÀ K'Ẹ TỌ WÒ. OYIN-MỌMỌ.!

EDITOR "Eko Akete" npete ati sọ ọrọ Asọye (*A public Lecture*) nipa Bombàta-ninu-Iwe DR EDWARD WILMOT BLYDEN, gẹgẹ bi o ti ṣe ãyan ki awa ọmọ-Iya rẹ lè pi Ẹko Giga ti yio si yè koro. A o ṣe ipade na ni Ile-iwe Ita Tinubu ti awọn Sanmari ibẹ̀ ti yõda fun wa, lai gba kọbọ, ni *Friday* ọjọ kọkandilọgbọn oṣu yi, a o si ṣe akanṣe idawo (*Donations*) fun iranlọwọ Iwe-irohin yi. Ipade na yio si silẹ fun ẹnikẹni: Ọgbẹni C. W. FAWLKNER-SHAW akọwe agbà ti Ile-iṣẹ Olori Ọkọ-ilẹ ti Nigeria l' Ebute Mẹta ni yio ṣe Alaga Ipade yungba-yungba yi ni agogo mẹjọ alẹ ọjọ na. Ani ireti pe gbogbo awọn to ba fẹ re-re Ilu wọn lọna bayi ki yio gbe ẹhin lọjọ na.

### Ẹ KÚ EWU ỌDÚN.!!!

Ki a to tun tẹ iwe yi jade lọsẹ to mb Ọdun Keresimesi yio ti de, yio si ti re kọ lọ, njẹ nitorina, a ki awọn ọrẹ wa nib gbogbo, ni akisilẹ. Ẹ kú ewu ọdun.


### The very Books you need!!

| | |
|---|---|
| General knowledge Test papers | 1/- |
| Key to above | 2/- |
| Ready's precis and precis writing with key | 3/6 |
| Forks Essays and how to write them | 2/9 |
| Dixon's English Idioms „ „ | 2/6 |
| Nancanow's "Notes in Hygiene" | 1/6 |

THE "ORA" BOOK SYNDICATE,
(P.O. Box 278)
*33, Obun Eko Street, Lagos.*


### INA KU F' ERU BOJU!

A gbọ iku ẹni re, oniwa tutu ati Olufẹkansin ti Mrs. Eller Bernadine ti o ṣẹlẹ ni Wednesday 13th *December*, lẹhin aisan ọjọ diẹ. Iya ẹni re yi ṣi wa laiye. Iya Ige, Labisi, Ayọ, Adeniran ati Adetọla ni ologbe yi. A ba awọn ọmọ rẹ wọnyi kẹdun; ki Ọlọrun ko ṣe iya fun wọn. A ba awọn ẹbi rẹ kẹdun ati Ọkọ rẹ pẹlu ki Ọlọrun tuu a'nu.

### AWỌN ẸGBẸ IFẸ TI IYA-AFIN
#### IJỌ WESLEY NI OLOWOGBOWO DA BIRA

Kugn ni ere ti awọn ọmọ ẹgbẹ yi ṣe ni Ile-iranti Afari-Ogun l'ẹhin Gbẹli ni *Friday*, ọjọ kẹdogun oṣu yi: orin npe orin rannṣẹ, ere pataki ti nwọn ṣe ti a npe ni "IBI-IYAWO DOLLY" jẹ kolẹgbẹ. A ba Ọgbẹni wa C. W. Faulkner-Shaw Baba-isalẹ Ẹgbẹ na, Iya afin Vashti Euba Akọwe ati awọn jakan-jakan ẹgbẹ na yọ fun ẹyẹ alẹ ọjọ yi, bẹ si ni a ba Iya-afin Mabel Benjamni yọ fun bi o ti ṣe iṣẹ rẹ bi Agba awọn ti a pe sibẹ, si ni alẹ na.

## OPEN LETTERS No. 12.

To A. W Thomas Esq.
*Ex-President,*
African Bethel Church Organisation.
Ebun House,
86, Odunfa Street, Lagos.

Dear Ex-President,

It is a thousand pities to note that when circumstances culminated in the resignation of your post in which you have been wielding the presidential *baton*, these twenty years, we were still in the womb of time.

Now that we are a living entity, we would ask you in all seriousness to bury the hatchet by overlooking all what had passed which rightly or wrongly has been distasteful to you, and once more, to cast your lot with the organisation with which you have thought it fit to identify yourself, even at a time when your personal friends—many of whom, alas, have since "joined the great majority"—had not the courage of their conviction to come out boldly as you have done, but were content to play the sneaking-Nicodamuses, whilst in your case, you dare to call a spade a spade by leaving *en masse* and of your own accord, the church of your birth for that of your adoption and soil.

Be Christ-like in patience and so remove the generally accepted reproach that we Africans are anything but enduring in any racial movement such as this.

Would you sigh again for the "flesh-pots of Egypt?" perish the thought!!!

Think of this, and remember your many years' devoted services to that struggling organisation.

May we hope?

Eko Akete.

## OUR BOGUS CANDIDATES.

To the Editor, Eko Akete.

Sir,—May I know through any information at hand when and where on earth is the name of a local Editor (having one year's public carreer behind him) mentioned among possible candidates to the new Council of Government?

Indeed, one who, and who alone, thinks himself thrown to the fore by a juvenile paper started last year, is a great dreamer—almost as great as Danfodio of the north.

Yours etc.,
A Voter.

## THE AFRICAN CHURCH.

*Resolutions passed at the Great Public Meeting held at Bethel Church, Lagos, on Monday, 18th December, 1922, in connection with the 21st Anniversary Celebration.*

RESOLUTION 1.

"That praise and thanks be given to God for (*a*) the eastablishment of the African Church, and the great mercy bestowed on her during the past 21 years, more especially, for the richness of His goodness, for-bearance, long-soffering, guidance and protection during the evil days of quarrels and seperation and (*b*) assistace received from the Local Government."

*Mover:*—Dada-Adeshigbin, Esqr.,
*Seconder:*—Adol: E. Coates, Esqr.,

RESOLUTION 2.

"That thanks be given to God for the Re-union effected in the African Church Organisation, (*a*) for the creation of African Communion, (*c*) for the spirit of love and union existing in all African Churches of local origin and management, and (*d*) for opening the hearts of the Africans to desire and thirst for the African Church."

*Mover:*—S. A. Jibowu, Esqr.,
*Seconder:*—J. A. Oshodi, Esq.,

RESOLUTION 3.

"That prayers and intercession be made unto God for the special power of the Holy Ghost on the African Churches now re-united, on her ministers, officers and members, that their lives and works may lead this Church to become The

African National Christian Religion and promote the spiritual life of the Race, (*b*) for special blessings on His Excellency the Governor and his Officers, Native Kings, Chiefs and their Council Members, (*c*) for those African Churches that are being persecuted in the interior, and (*d*) that the understanding of Foreign Missionaries may be enlightened to view the African Church as the legitimate result of their good work and stop persecuting it."

*Mover*:—O. T. ṢOMEFUN, ESQ.

*Seconder*:—Revd. Supdt, G. A. OKE.

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY DECEMBER, 23, 1922.

### KERESIMESI ỌDUN DE!

Bi ere bi ẹwa Ọdun miran tun dun ba ni lori ile aiye, ani Ọdun ayajọ Ibi Kristi. Bi o tilẹ jẹ pe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni awọn enia igba lailai fi iranti ọjọ nla yi si, sibẹ a sọ pe iṣiye meji wa ninu rẹ nitori pe o jẹ ọjọ ti awọn ara Ilu Rome igba ni ya sọtọ fun bibọ Orun ti o ṣẹṣẹ la otutu ja, bi igbati a ṣẹṣẹ bi Ọmọ-agbo; nitori eyi ni awọn Olufọkan sin igbana kuku fi ohun ṣọkan lati ma ṣe ayajọ na ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu *December*, lọdọdun

Ko si onigbagbọ ti ko mọ pe lasiko kika enia ni Jerusalẹmu ni igba aiye AUGUSTUS CAESAR Ọba *Rome* ni a bi JESU ẹni ti apele rẹ njẹ KRISTI; ṣiwaju rẹ awọn Woli nla-nla ti lo igba, awọn bi *Buddha, Confucius, Zoaraster* ati Asoka ọba ṣugbọn gbogbo awọn wọnyi ni KRISTI firi bi ẹgba ti firi okan nipa iṣẹ ifẹ ati iṣẹ rere rẹ lode aiye to ta ti gbogbo wọn yọ; pataki ẹkọ rẹ ni pe Ọlọrun ni Baba gbogbo wa; a le jẹri si eyi nibi ti o gbe sọ ninu ọkan ninu awọn Ihin-rere pe" Emi nlọ sọdọ Baba mi ati Baba nyin, sọdọ Ọlọrun mi ati Ọlọrun nyin. Ẹwẹ Oba Iku Baba yeye, apabi-ẹkun ti a npe ni NAPOLEON ti ilu Franse "yo-nbo" Iṣẹ ifẹ Kristi ba yi nigba kan pe "On, ALEXANDER, CÆSAR, ati CHARLEMAGNE ti ṣẹgun gba ilu pupọ, ṣugbọn ki ni aṣiri iṣẹgun wa na? jagidi-gagan ni; JESU KRISTI nikan ṣoṣo lo fi Ifẹ ṣẹgun gbogbo aiye, tobẹ to fi jẹ pe ọgọrọ enia ni agbaye lo mura tan lati fi ẹmi wọn lelẹ fun u. Njẹ ẹnyin onigbagbọ ẹlẹgbẹ wa, ẹri wo lo tun ju eyi lọ? nitorina lo ṣe yẹ gidigidi ki a kiyesara gẹgẹ bi a ti nṣe ajọyọ Ọdun yi: ko ma si aṣe yọ yẹ, ki imuti para, lilọ ọgọ, kunmọ ati ọrọ-ma-so--ndo-ki ko jina si wa ninu gbogbo ariya wa: o si yẹ ka ṣe iranti awọn to wa ni akete aisan awọn to wa ninu Ọgba ẹwọn ati awọn to ti fi ilẹ bora bi aṣọ, ti nwọn ba wa ṣe ọdun ti eṣi ṣugbọn ti a fẹ ku ni Ọdun ni,!!! ki Baba, abọ'wọ gbọgbọ rọ nyọ 'mọ rẹ l'ọ fin ma ṣai yọ wa kuro ni gbogbo Ọfin aiye yi.

Lakotan a ki gbogbo ẹnyin enia wa nibikibi to wun ki ẹ wa, Ẹ ku ewu ọdun. Aṣeyi ṣ'amọdun. Ẹ ba wa fi ẹsẹ si orin ọdun yi:—

Kuru kuru Bete Amodun,
Bayi l'ẹ o ba wa, Amọdun!!!

### ERIN WO L'OKE AMI—LÀLÀ

A-gbọ-ju-'gba-nu ni a gbọ iku Ọgbẹni OBEDIAH HUTCHINSON WILLIAMS ti o ṣẹlẹ ni alẹ *Teusday* ọsẹ yi ni Ile rẹ 69, Ita Victoria.

A o sọ ọrọ diẹ nipa ti Iwa-aimọ-tara-ẹni nikan ti ọgbẹni yi, nigbati o ba ṣe.

A gbọ pe o di ẹni ọdun mejilelọgọta ki o to tẹri gba 'ṣọ.

A ba ọmọ rẹ ti o mbẹ ni Ilu Ọba nisisiyi—Ọgbẹni AYỌ WILLIAMS ati awọn ẹbi rẹ miran kẹdun ọfọ nla yi.

### GBÉRÈ, ỌMỌ OLOWO AKE!

A ba aya Balẹ Ilu (MRS. HENRY CARR) yọ fun yiyọri ere ti awọn oyinbo ati awọn enia wa ṣe (*Tennis Match*) ni *Wednesday* ọsẹ yi ni apa Ile DR. ADENIYI JONES lati agogo marun oju alẹ titi de agogo mẹfa abọ. Iya-afin yi lo ṣe oju awọn elere na. Gomina agba SIR, HUGH CLIFFORD si wa sibẹ ko si lọ titi a fi pari ere na.

Awọn sanmari ti a fi iwe pe t'ọkunrin t'obinrin wa, nwọn si ṣe idawo to jọju fun iran lọwọ Ile-iwe giga ti AYABA LADY CLIFFORD nṣayan ati kọ fun anfani awọn arabinrin wa nihin.

### AIYE LU J' ARA.

A ba awọn ara Ijẹbu Rẹmọ yọ fun Ọna *Motor* ti a fẹ ṣe lati ilu wọn wa si Eko.

Inu wa dun pe a ko ni pẹ ṣe ọna na pari nitori oyinbo ti yio jẹ Alabojuto ati pe ṣiṣẹ-ti-ọ-tẹ'wọ-gb'owo ni, ki iṣe ọfẹ *free labour*. Nigbati a ba ṣe ọna na tan Ijẹbu Rẹmọ yio di duro-de-mi-mo-nlọ-s'ọde-kabọ fun awọn ara Eko.

"Yiyẹ ni iy' ẹiyẹle." A yẹ ọ Gomina fun yiyọda ti o yọda pe ki a ṣe ọna yi.

Ẹnyin olowo gbogbo a ki nyin ku afojusọna anfani ti ọna yi yio mu wa ki Ọlọrun jẹ ki o ṣoju ẹmi wa o.

### LAGOS TOWN COUNCIL. PUBLIC NOTICE.

The public are requested to take out their Licences for 1923 according to the following Time Table.

All Licences will be issued from the Council Offices, Catholic Mission Street.

No Licences will be issued until the 19th March, 1923, except as follow :—

Market dues, Liquor, Auctioneers and Dog Licences, from 2nd January to 6th January inclusive.

Motor Vehicle, Motor Cycle and driving Licences, from 8th January to 27th January inclusive.

Carriage Bath Chair, Rickshaw, Go-cart, Truck Barrow, Hand Cart, Licences, from 29th January to 10th February inclucive.

Bicycle and Tricycle Licences, from 12th February to 5th March inclusive.

Petrolem Licences, from 6th Mrach to 17th March inclusive.

Licences will be issued each day from 9 a.m. ill 12 noon and on Saturdays from 9 a.m. to 11 a.m.

A. W. S. RUMENS.
*Secretary, Town Council.*

Lagos Nigeria,
14th December, 1922

## LAGOS TOWN COUNCIL
## PUBLIC NOTICE

Notice is hereby given that on and after the 1st January, 1923, the following revised Motor Vehicle License Fees, will come into opration in accordance with Regulation No. 26/1922 (Schedule III.)

1. Motor Cycle (with or without Side-car) £1 10 0
2. Motor Vehicle weight unladen not exceeding 12 Cwt. £3 0 0
3. Motor Vehicle weight unladen exceeding 12 Cwt. but not exceeding 30 cwt. £6 6 0
4. Motor Vehicle weight unladen exceeding 30 cwt. but not exceeding 50 cwt. £12 12
5. Motor Vehicle weight unlading exceeding 50 cwt. £45 0 0
6. Traler, weight unladen not exceeding 10 cwt. £1 1 0
7. Trailer weight unlading exceeding 10 cwt. £2 2 0
8. Dealers License. £4 4 0

When a License is issued after April 1st and before July 1st, or on or after July 1st and before October 1st or on or after October 1st a reduction of one quarter, or one half or three qaurters of the above fees may be allowed respectively.

"Weight" means the weight of the Vehicle exclusive of the weight of any water or fuel.

A. W. S. RUMENS,
*Secretary Town, Council*

Lagos Nigeria,
14th December, 1922.

## *Oran Ilu Nigeria No. 6.*

Aṣaro ti ogbẹni Herbert Macaulay oloye C.E. ṣe lori ọrọ ti Dr. John Randle oloye M.B., C.M. sọ ni ilu oyinbo ti a tẹ si Iwe-irohin ti a npe ni West Africa ti ọjọ keji oṣu September 1922.

### THE PEOPLE'S UNION

5. "Lati ma purọ fa, ko fẹ pe ki enia ni ogbọn ati ma wa a nikan, ṣugbọn o nfẹ ki enia ni iṣoye to gbo."

Ni titẹle aṣa ti Gomina Sir William Macgregor ẹniti o fẹran awọn Ọba ati Ijoye Eko ati ti agbegbe rẹ da silẹ, Gomina Sir Walter Egerton pe ipade igbimọ enia dudu (*Central Native Council*) si ile Ọba ni ijọ ogun oṣu *July 1908*, awọn ti o wa si ipade ni wọnyi :—

Gomina (Baba Ẹgbẹ) Prince Eleko (Baba Isalẹ) Chief Ojora, Chief Eletu, Chief Aromire, Chief Aṣogbọn, Sule Giwa, Abibu Lemọmu, Alli Balogun, Braimah Lemọmu, Oṣonosi, Kasumu Giwa, Yesufu Ọba, Ọduntan Adamaja, Asani Giwa, Musa Koko bi oko, Sufianu Giwa ati Amidu Akarugbana.

Awọn ti ko le wa :—Chief Salawe, Balẹ Ẹpẹ, Balẹ Ijaye ni Ebute Mẹta, Balogun Ijaye ti Ebute Mẹta, Sunmọnu Baṣọrun, Akirigbo Ṣagunu, Seidu Olowu, Baṣọrun Ilaro ati Seriki Abasi ti Agbadarigi.

Gomina fi han igbimọ ero ti nwọn ngba nipa ti fi fa omi si Eko, lẹhin ti o si ti la a daradara tan, o ni ẹniti o ba fẹ sọrọ, ki o sọ.

Enia mẹsan pẹlu Eleko ba igbimọ sọrọ, lẹhin ti nwọn sọrọ tan, Gomina pari ipade na pẹlu ọrọ wọnyi pe :—

"Mo dupẹ lọwọ yin fun wiwa ti ẹ wa, mo si ro pe ẹ o lọ tun ọrọ na daro. Bi ẹ ba si tun ro nkan miran yato si eyiti ẹ sọ yi, ki ẹ jẹ ki nmọ." A si fi ipade na di ijọmiran.

Were lẹhin ipade yi, Dr. John Randle pẹlu Dr. Ọbasa di ẹniti o nfun Eleko ati awọn Ijoye onifila funfun Ekọ ni imọran lọfẹ, nwọn si mu imọran wa pe ki awọn ara ilu da ṣile kọkan lati ri owo fun ati ja ija ti omi ti nwọn o fa wa si Eko ti a o si ma sanwo rẹ.

Awọn obinrin Eko ati agbegbe rẹ bẹrẹ si owo yi da pẹlu itara, laipẹ owo yi ju ẹgbẹrun Pọnwọn lọ, pẹlu ireti asan pe akọwe ipade ilu ti o ṣe ileri fun wọn pe on nlọ si ilu oyinbo lati da Ijọba lọwọ duro ki o ma le gba owo omi lọwọ wọn, ki yio jẹ ki awọn san kọbọ aladorin si inu apo Ijọba.

Bi nwọn ti ṣe k' owo jọ fun Ẹgbẹ *People's Union* niyi. Rogbodiyan yi de gongo ni *November 1908* nigbati awọn Oloye kọ iwe kan ṣọwọ si Gomina ni

ijọ kẹrinlelogun oşu *November 1908* ti nwọn ni, ofin ti Ijọba fẹ mu lọ si Ajọ igbimọ aşofin nipa ti didiyele ile nitori ati mọ iye owo omi ti nwọn o gba lori rẹ, ki o da a duro na, tabi ki nwọn ma iti sọ di ofin titi yio fi ri iwe ẹbẹ ti Dr. Randle ati awọn igbimọ rẹ kọ.

Gomina da esi iwe yi pada. O si fi ran akọwe Ọba ni ijọ kanna. Ijọ meji lẹhin eyi, ni ijọ kẹrindilogbon oşu *November* 1908 a şe ipade ilu kan l' Ẹnu Ọwa, ninu ipade yi nşe ni Dr John Randle ati Dr. Ọbasa nşe bi alarakumajagba lori agba larin ogunlogo awọn Imale ati Yoruba ilẹ yi, awọn onifila funfun papa nbẹ nibẹ, ọrọ ışiri ti nwọn si sọ nibẹ mu ọkan awọn ara ilu yigbi si omi ti Ijọba ni awọn fẹ mu wa si ilu ati ti a o si ma san owo lori re. Ninu ipade yi ipinnu mẹrin ni nwon şe pe, nwọn ko fẹ omi ti nwọn o ma san owo fun ; "pe ki a se iwe ẹbẹ lọ sọdọ akọwe Ijọba agba 'ni ilu oyinbo pe a ko tẹ omi yi, eyiti yio ba owo jẹ iyẹn ti ko ba tilẹ ni ibajẹ "patapata" "peki a fi waya şowọ si ilo Ọba ; ati pe ki a fi ẹda ipinnu wonyi ati ti waya ti a o fi şowọ si *London* şọwọ si Gomina." Lakoko yi, ko iti si "rukerudo awọn Imale." Tabi mo se.?

Bẹni Dr. John Randle ati awọn miran da ina nkan si Ijọba lati odun 1908 titi di ijọ kọkandilogun oşu *April 1916* (o di ogun oşu ti ogun nla ni ti şẹlẹ nigbati Lieut Colonel H. C. Moorhouse, C.M.G., D.S.O., fi iwe No. L C 20/1915 şọwọ si awọn ti o f' ori fun Ijọba yi, ti nwọn si jẹ aşaju enia dudu ; ẹsẹ keji iwe na wi bayi pe :—

"Gomina ri esi gba si iwe rẹ ti o fi mu iwe ẹbẹ yin ti o kọ ni ọjọ ogun oşu *November 1915* lọ, a si ni ki nsọ fun ọ pe akọwe agba ni on ko tun jẹ ba ọ sọrọ na mọ."

Ni şoki eyi ni itan ti ibi, iwalaiye ati kiku Ẹgbẹ *People's Union*, aşaju awọn ẹniti akọwe agba ti o ntọju ilu amọna Gẹsi sọ fun ninu oşu *August 1915* "pe işẹ ẹniti o ba di opo Ijọba mu ni lati kọkọ tẹriba fun awọn ofin ilu rẹ."

Ohun ti o gbẹhin ọrọ yi ni, Eleko, awọn onifila funfun ati awọn ara ilu ko ni igbẹkẹle si ikojẹ Dr. John Randle ati Dr. Ọbasa mọ, awọn ẹniti ko to da ọwọ agbara ilọsiwaju duro, nigbati awọn enia nri fun 'ra wọn pe nwọn fi *Number* mọ ile wọn, ti wọn si ri pe a ngbẹ koto, a si ngbe ohun ti omi yio ma gba inu rẹ koja sinu re larin Eko nibi ; ti Gomina agba si lọ şi omi yi ni popo ẹhin Ọgba ; ati paripari gbogbo rẹ ti nwọn si ri awọn gbowogbowo ninu aşọ kaki l' ẹnu ọna wọn.

Nigbana ni awọn enia wọnyi mọ pe awọn ogboni wọn ko lagbara ohun ti nwọn ti nso pe awọn yio şe. Lojiji ni nwọn ji l' oju oran ti nwọn ri pe gbogbo ẹnu ti nwọn nfọn l' ẹnu Ọwa l' ori agba ko ju "ofo ijọ keji ọja" lọ.

Ọpọlọpọ awọn enia kuro ninu Ẹgbẹ *People's Union* nitori eyi, Ẹgbẹ na ko si dabi alara mọ.

Ọgbẹni ọlọla Winston Churchill sọ bayi nigba kan pe :—

"Lati yi ero rẹ pada jẹ ọkan ; lati wa tun yipada si awọn ti o ti ntẹle amọran ti o kọko fun wọn jẹ omiran."

Nitoripe Eleko sọ pe on ko mọ nkan ti o wa ninu waya ti nwọn fi şọwọ si *London* ni ijọ kọkandilogun oşu *July* 1915 eyiti akọwe agba tọka si pe "a nfi ẹjẹ tẹmbẹlẹkun sinu tu 'tọ funfun jade" wa ninu rẹ, ati nitoripe oloye Ọjọra (ẹniti orukọ rẹ wa ninu waya na gẹgẹ bi alaga, ti Dr. Ọbasa si je akọwe) sọ fun Gomina pe on nko mọ pe ọrọ idırẹ si Ijọba nbẹ ninu rẹ, bẹni awọn aşaju nke kikan pe Eleko ati oloye Ọjọra awọn ẹniti ko mọ iwe ka mọ nkan ti awọn kọ sinu waya daradara ; lati igbana ni awọn enia wọnyı korira Eleko, ti oloye Ọjọra si ju ijoko rẹ bi alaga nu, a si wa gbe Dr. John Randle ọga aşelu si ipo alagba.

Bi nwọn ba ju ifẹ ati igbẹkẹle awọn enia nu, ti awọn ti o ti tẹle amọran Dr. John Randle ati awọn onigberaga ekeji rẹ, ba kọ wọn silẹ, awọn ti a ti tanjẹ pe a ko le fa omi wa si ilu yi lailai, ati pe t' ọmode t' agba, l' ọkunrin l' obinrin, ẹnikan ki yio sanwo omi ; bi awọn aşaju nwọnyi ba ri pe awọn ti o ti ntẹle wọn ko gbẹkẹle wọn mọ, ohun ti o mu wa ni pe awọn enia ri gbangba pe ibo ikoko la ti nbo wọn, nwon wa mọ pe iwa iwere ni nwọn ti nhu fun nkan ọdun mẹjọ, ani ọdun ti o kun fun ọpọlọpọ ijiya.

Nipa ti titako ti o ti ntako ẹbẹ ti a nbẹ fun ati yan enia fun 'ra ẹni si Igbimọ Ijọba, Dr. Randle ti yi ero rẹ pada, o wa sọ pe ọna ti a fi si ilana titun ti *Nigeria* dun mọ on ninu. O yi ero rẹ pada nipa ti Eleko to jẹ olori ile Dosunmu, ẹniti o jọ bọba rẹ daradara nipa pe ọgbọn rẹ ko to nkan.

Ẹnikẹni ko ni lati ba Dr. Randle ja si eyi, şugbọn ẹşe ti yio fi wa kọju ija si ọmọ alade, ẹniti o ti tẹle imọran rẹ ri lati ba Ijọba şe kokowa, lati ọdun 1908 de 1916, ti o si wa nwa aye lọnakọna lati jẹ ki a jẹ n' ya, ki a doju ti i, ki a si wa a lọ.

Ilu ọmọ alade yi, dajudaju, o san Dr. Randle dada laibere bi ọmọ-alade na lọgbọn tabi ko ni. Nitori "ede aiyede hanun" wa larin Eleko ati Dr. John Randle pẹlu awọn isọngbe rẹ, awọn ti a ka si, ti a si nba lo gẹgẹ bi aşaju awọn enia dudu bi nwọn fẹ ti nwọn kọ, nitorina nigbati Ijọba (labẹ abojuto ọgbẹni A. G. Boyle) şişe nipa huhuwa aitọ si ẹni rere ti ko gbọn tobẹ, eyiti o bi ẹgbẹgbẹrun enia ninu ti nwọn fi lọ ri Gomina Sir Hugh Clifford pe ki o şe ẹtọ nidi ọran na, o dun Dr. John Randle ati awọn ọmọlẹhin rẹ pe

ọfa ti wọn kọ ta ko mu u, nitorina gbogbo nwọn ati awọn onişẹ wọn bẹrẹ si wa ọna kita lati ba işe ọmọ alade yi jẹ, ẹniti o ti tẹle imọran wọn ri, nitori ki a le sọ pe ọna ti nwọn la silẹ lati fi ba a jẹ dara.

"O jẹ ohun ti o dara ju lati şe idariji, o si jẹ iwa akin lati gan ju pe ki a gbẹsan ibi lọ."

Bi o ba da DR. JOHN RANDLE loju dada pe Ẹgbẹ *Peoples Union* şi wa laiye lati igba ti o ti da a silẹ, kini mu ti o tun lọ da *Lagos Reform Club* silẹ, ti on papa si jẹ Baba ẹgbẹ lori ọmọ ẹgbẹ mẹrinla pere?

E ha şe ti ẹgbẹ *People's Union* ko fi kọ iwe aşaro ti nwọn gba lori Igbimọ ti o joko lori owo ati owo ori ti ilẹ enia dudu ni iwọ orun Afrika; dajudaju nwọn le sọ eyi lai fi tẹmbẹlẹkun bọ inu rẹ. Ẹgbẹ *Lagos Reform Club* eyiti DR. JOHN RANDLE jẹ Baba ẹgbẹ rẹ mẹrinla f' ọwọ si şọwọ si awọn igbimọ yi, eyi si han ninu ori 129 titi de 131 ti iwe ẹri ti awọn Igbimọ na eyiti SIR HUGH CLIFFORD jẹ alakoso wọn l'ọdun to koja. Nibo ni *People's Union* wa nigbana. DR. JOHN RANDLE ni Baba ẹgbẹ awọn ẹgbẹ ilu mejeji yi. Kini ha de si Ẹgbẹ *People's Union* lati igbati ọgbẹni H. F. PEET ti fi ọgbọn ẹrọ ti a da fun lilo ọmọ enia ntu omi Iju ti o mọ gara si ilu Eko, ti ọgbẹni A. W. S. RUMEN si ngba Ẹgbẹgbẹrun pọun sinu apo Munisipal lọdọdun lọwọ awọn aşaju ati ọmọ ẹgbẹ *People's Union* ati lọwọ awọn ara ilu Eko.

Lẹhin igba ti nwọn ti ti ilu bayi fun ọdun mẹjọ gbako lati ma a şe tankanmọ si Ijọba, lojiji DR. JOHN RANDLE ja nwọn silẹ, o si tun wa koju 'ja si awọn ti o ti ntẹle imọran rẹ.

O wa di ọrẹ Balẹ ilu nitotọ, ẹni gẹgẹ bi rẹ ni Afin Ọba, ti o le ma tun tirẹ şe lọdọ aşoju Ọba ni akoko ati igba ti o ba wọ.

On nikan ko ni oyin—ti o nkun yun leti onişẹ Ọba pataki yi lati ọdun 1916, ti nwọn nwa tanna-tanna totọ—ti o le ju ara rẹ sinu ẹrẹ ijatilẹ nikẹhin gẹgẹ bi ala ti o dun julọ, ti o si gbadun ju, şugbọn ti a parun pẹlu ọpọlọpọ ikanu ati ọşe.

"Nigbati ọla ba wa si ọdọ rẹ mura lati di i mu şugbọn ma wara ati di i mu titi yio fi sunmọ ọ."

*Koi ti pari.*

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pill sand get instant relief. It makes a man a man, In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neurasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of the trouble-some Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store — VIDAL. R. COLE

P. O. Box 201 ;109 Broad Street Lagos.

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER.

OYINBO GERMAN ONIŞOWO NI HAMBURG

fẹ ka sọ fun nyin pe ẹ le wa wo orişirişi irepe ọja pẹlu iwe-ọja on ni.

Ile-Owo rẹ *No. 7*, Ita Labinjọ, leti Ita William l' Eko.

Yi o tete bojuto iwe ti ẹ ba kọ si i, ti ẹ ba si fi sinu apoti iwe rẹ No. 459, ni ile-ipinwe l'Eko, ati iwe-ti ọja ti enia ba fẹ ranşẹ lọdọ rẹ. O yẹ ki awọn onibara rẹ tete wa ranşẹ ọja wọn fun akoko oşu Awẹ ki o ba le tete de: oniruru ọja lo le ranşẹ fun ẹnikẹni, o si ni ọgọrọ ọja lorişirişi.

Ẹ wa wo o !!!

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

ni wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Şẹrẹkẹ şin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

---

"EKO AKETE"

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ awọn Aşoju wa wọnyi.

LAGOS.

1. Ajenifuja Stores, 109 Broad Street.

IBADAN.

Ọgbẹni A. M. Suberu Santo's Street, Igbagi House.

ZARIA.

Ọgbẹni A. Ẹkundayọ Cole, Accounts Office.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

### ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Arọ,
6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibi-un.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

### ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. do | do |
| 9 a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E Johnson |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

### WESLEYAN

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m.—Ereko | do do |
| 7 p.m. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do do |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Rev. J. A. Pearce |
| 7 p.m. | Bro. Cecil Byass |

### AFRICAN (COMMUNION)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | „ Supt. G. A. Oke |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 4 p.m. | do do |
| 9 a.m.—Bethel | Bro. A. O. Thomas |
| 6.30 p.m. | Rev. E. A. Akiọla |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Bro. Sam Johnson |
| 4.30 p.m. | Rev. I. O. Oyekunle |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | Bro. Joseph Dekọya |

### EBENEZER

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. Joseph Bandele |
| 6.30 p.m. | Bro. E. C. Alabi |

### BROTHERHOOD

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

(Harvest Thanksgiving Service.)

### St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

### AHMADIA

6 a.m.—Fajir Service Bro. Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ
(Bamgboṣe Street.)

### COLONIAL CHURCH. (ODAN)

December 24th, 4th Sunday in Advent.—
8 a.m.—Holy Communion Rev. H. A. Lewis
6.45 p.m.—Evensong followed by Carols do.

Christmas Day.

8 a.m.—Holy Communion. do.
10 a.m.—Morning Prayer without Sermon, followed by Holy Communion.

BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni

"MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara ẹja ọ.

---

Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o ṣi "Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,

Ogun rẹ jire.

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo oja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7. Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAŞINI-ARANŞO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAŞINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara. Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipon, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-oja yi, to wa ni Popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO. Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Own-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kotu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si oja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififọ. Inarun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sibin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.

Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ rẹ ndan?

Işẹ Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,

*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
168, Moloney Bridge St.
P. O Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

## F. BLACKBURN & Co.,

Jẹ awọn Oyinbo onisowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorisirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'Eko.

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a ṣọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko.
Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

---

AWỌN ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18 GERMANY.

Jẹ Awọn onisowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranṣẹ ọja fun enikẹni to ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jo enia loju.

Ko si ewu kankan ti fi fi ọja-koja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onisowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti ng' oku l' ọrun?
Ki la ti ng' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS. WRITER AND LECTURER.